**LAKAYE ỌRỌ**

Ẹniti oye ku fun a ma a gan Ọmọnikeji rẹ, ṣugbọn ẹni oye a pa ẹnu rẹ mọ.

Alayidayida enia da ija silẹ; asọrọ kẹlẹ ya awọn ọrẹ ni ipa.

# ÌROHIN ÌMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**OWE**

Bi owe bi owe ni a nlu ilu Agidigbo, Ọlogbọn ni njo o, Ọmọran ni mọ ọ, Nitoripe ewe koko ni nwọn fi ṣe awọn rẹ, igi ganmuganmu ni nwọn fi nlu u bẹni ko gbọdọ fava ko si gbọdọ ma dun.

VOL. VI No. 348 MONDAY SEPTEMBER 17 — SEPTEMBER 23 1962 KỌBỌ MEJI (2d)

# OLOYE AGBAJE K'ỌJU AKINTỌLA S'ORUN-ALẸ

IBADAN.- Ibanuje dori Agba kodo ni irohin ti o kan wa ku laipẹ yi jẹ fun Oloye S. L. Akintọla Olori ẹgbẹ Ọlọmọjukutu nwọn npe ni "U. P. P.", nigbati Oloye M. F. Agbaje ti iṣe ọkan ninu awọn amugbalẹgbẹ ẹgbẹ Ọlọmọjukutu na tẹlẹri fi aake kọri ti o si kọ jalẹ wipe on ko ṣe ẹgbẹ na mọ, on yio kuku pada sinu Ẹgbẹ Alakuko (N. C. N. C.) ti on ti wa tẹlẹri.

Oro yi sẹlẹ nigbati gbogbo awọn ti awọn ti wa ninu Ẹgbẹ Akintọla ṣe ipade kan ninu ile Oloye Agbaje ni adugbo Ayẹyẹ ni Ibadan ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejọ Oṣu yi.



*OLOYE S. L. AKINTỌLA*
*Olori ẹgbẹ Ọlọmọjukutu (U. P. P.)*

Gbogbo ile lo kun sọsọ, ti ko si gba ero ninu ipade ti gbogbo awọn Ọmọ Ẹgbẹ Akintọla U. P. P ṣe.

Ọgbẹni Agbaje fi ye gbogbo enia ninu Ipade na wipe, On ti ṣe tan nisisiyi lati kuro ninu ẹgbẹ na, ki ṣe gẹgẹbi ifẹ-inu on ṣugbọn gẹgẹbi ifẹ awọn enia on ni. Oloye Agbaje tun sọ siwaju si i wipe ki i iṣe wipe nitoripe nkan ti bẹrẹsi buru si i ninu ẹgbẹ Akintọla U.- P. P. ni on ṣe kuro, tabi boya on ti jere nkankan lo mu on kuro. Oloye Agbaje sọ wipe lati igbati rogbodiyan ti bẹrẹ ni on ti ri i wipe gbogbo Ọmọ Ibadan ko fara mọ e eto na. diẹ ninu wọn lo si fi ara mọ ọ ati wipe awọn ti nwọn ko fi ara mọ pọju awọn ti o fara mọ lọ nigbati on nja fun ẹgbẹ Akintọla.

Oloye Agbaje tun sọ siwaju si i wipe, awọn ti awọn fara mọ ẹgbẹ Akintola ti bẹrẹsi ri i nisisiyi wipe, awọn ti ko tilẹ ba awọn bẹrẹ ẹgbẹ na ti bẹrẹsi ni anfani ju awọn ti awọn bẹrẹ re lọ.

Nigbati Oniwe Irohin kan bi i lere pe nje o tun ma a ja fun ẹgbẹ Akintọla ninu Iwadi Adajọ Coker?" Oloye na ni "Bi awọn enia na ba ni igbẹkẹle si on, on le ṣe e, ṣugbọn o ku si ọwọ wọn.



*OLOYE M. F. AGBAJE*

Ni ipari ọrọ rẹ ninu ipade na, ọgbẹni Agbaje sọ wipe on ti fi ẹgbẹ Akintọla silẹ on si ti pada si ẹgbẹ Alakuko (N. C. N. C.).

## Gbadamọsi pe Ajao l'ẹjọ

EKO:— Oloye S. O. Gbadamọsi pe Ọmọ Ologbe J. A. Ajao lẹjọ, o si mbẹ kotu pe ki ọmọ Ologbe na Aderogba Ajao lọ san Ẹgbẹdọgbọn pọnun (£50, 000) nitoripe o ba orukọ on jẹ, pe on jẹ baba on (Ajao) nigbese, bẹni on Gbadamọsi ko jẹ Ajao ni Ọnini kan.

## Gbọmọgbọmọ kan ta Iya ati Ọmọ rẹ ni ẹgbẹfa pọnun

ONDO - Gbogbo ile ẹjọ lo kun sọsọ ti ẹsẹ ko si gba ero ni ọjọ kẹwa osu yi nigbati awọn Ọlọpa mu ọdaran kan, Sule Ayambẹ, wa si iwaju Adajọ agba, ọgbẹni, V. Akin Delumọ fun ẹsun pe, o ta Iya kan ati ọmọ rẹ ni ẹgbẹfa pọnun (£1,200).

Ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣejọ ṣe alaye niwaju Adajọ wipe ọdaran na lọ si ọdọ ọkunrin kan, Christain Ehoagu ni Ondo o si sọ fun un wipe ki o ba on wa enia lati ra iya kan ati ọmọ rẹ ti on mu bọ lati Ipinlẹ Ariwa.

Lẹsẹkẹsẹ ni ọgbẹni Ehoagu wa si Tẹṣan awọn ọlọpa ti o si wa sọ fun wọn. Nigbati awọn ọlọpa si ba a de ile ọdaran na, o ko iya ati ọmọ rẹ jade ninu iyara, awọn si ko owo fun un. bi o ti gba owo, (£1, 200) ti o si ka a tan ti o si fẹ ko wọle lọ, ni awọn ba mu u.

Ọdaran na gba wipe on jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa mu on fun, ni adajọ ba ni ki o lọ fi ẹwọn ọdun mẹwa jura.

## Onigbese kan lu Olowo rẹ pa

Ile ẹjọ giga Ibinni pa lọlọ nigbati Ọlọpa kan, Samuel Ijeben nrojọ niwaju Adajọ agba, Ọgbẹni Fatayi Williams, pe on ri awọn Ọdaran meji kan, O. Ikhuria ati J. Ememyon, ti nwọn bẹrẹsi lu Ọkunrin kan ti orukọ rẹ nje Thomas Ogbowan.

Ọlọpa na sọ wipe, nigbati Ọgbẹni Thomas wa sin gbese pọnun mẹrin (£4) ni ọdaran na ba mu apola-igi kan o si fi lu olowo rẹ lori, lẹsẹkẹsẹ o ṣubu lulẹ ọdaran na salọ ni on ba gbe ọkunrin na inu mọto ti on si lọ si ile-iwosan, ṣugbọn ọkunrin na ku ni ọjọ keji.

Adajọ yẹ gbigbọ ẹjọ na si gba miran.

Nwọn si ti ṣe ileri pe awọn ko ni ṣe bẹ mọ,a wọn yio si tun yọwọ kuro patapata ninu ọrọ Oṣelu.

Ṣugbọn awọn Oloye na ko ti ri esi lati ọdọ ọba Alayeluwa Adeniji Adele ati Minista Alamojuto Eko.

## Awọn Oloye Eko bẹbẹ

Awọn Oloye marun ti Ọba Kabiyesi Adeniji Adele rọloye laipẹ yi ti kọwe ẹbẹ si ọba na ati minista alamojuto Eko.

*ADVT. No. 151*

**Ṣe o ti lọ parọ owo atijọ ọwọ rẹ si OWO TITUN**

*TI ILẸ NAIJIRIA?*

O le parọ owo pepa korọnsi l'ọfẹ titi di ipari oṣu SEPTEMBER ti a wa ninu rẹ yi.

*Ti owo ṣile ati awọn owo wẹwẹ di ipari oṣu DECEMBER*

# ỌRỌ OLOTU

## Ẹ YE PAṢAGA ṢE

NINU iwe wa ọsẹ yi ni a ti ṣe kilọkilọ jade fun awọn ara ilu kan, nitori iku ojiji ti awọn ọdọmọkunrin nku nitori obinrin, awọn ti ko ku wa ninu idubulẹ aisan nisisiyi.

Awọn Ọlọpa Shomolu ko awọn panṣaga obinrin metala wa si kotu laipẹyi. Ohun ti o fa a ni wipe, ọmọdekunrin kan lọ si ile wọn, ṣugbọn ko gbadun lati ọjọ na mọ. O si wa ninu aisan bayi.

Ni aiye atijọ ko si ẹniti o ma fi panṣaga ṣe iṣẹ ti awọn enia ko ni ṣaiṣe yẹgẹdẹ rẹ de aye ti oju yio fi ti i, ti yio si fi tete siwọ ninu iṣẹ ibi na. Ṣugbọn awọn pansaga asiko yi ko ni itiju rara, nwọn ko mọ ibajẹ ti nwọn nfi ara wọn ṣe ati eyi ti nwọn nṣe si ẹlomiran si ayida, siṣe ni nwọn nfi ibajẹ ṣe ayọ.

Nwọn a ma a kun efun si oju, nwọn a ma a sirẹsi irun ori wọn, nwọn a si ma a kun ọda si ete, nwọn a wa dabi garenta, nwọn o si ma a gan idi wọn bi pẹpẹiyẹ kakiri ilu larọ, lọsan, ni irọlẹ, ni alẹ ati ni oru lati polowo ara wọn fun awọn ọkunrin.

A ti ri ọpọlọpọ awọn ọdọmọdekunrin ti nwọn ko mọ bi aiye ti ri, ti nwọn si tẹle awọn panṣaga wọnyi ti igbesi aiye wọn si ti baje patapata nitori eyi! Ko si ẹniti yio tẹle pansaga ti ko ni saiṣe abamọ. O yẹ, o si tọ ki ọmọkunrin ṣe iṣẹ, ki o si ni ọwo lọwọ, ki o si ni iyawo tirẹ. Egbe ni fun pansaga.

O dun mọ awa Oniwe IROHIN IMOLẸ pupọ lati ri pe awọn Ọlọpa ti berẹsi gbe ogun ti awọn panṣaga, ẹnikẹni ti nwọn ba ri pe panṣaga lo nṣe jẹun, nwọn a fi ofin mu u lọ si Kotu nibiti yio jẹ iya ẹkunrẹrẹ. A dupẹ lọwọ awọn Ọlọpa, nitori laisi aniani iṣẹ ribiribi ni nwọn nṣe fun ilu wa, a si ni ero pe nwọn yio tubọ mura si iṣẹ na.

# YẸYẸNATU!

## Oni yẹyẹ Eko

Olotu:- Mo bere rẹ nile, nwọn ni o lọ sile Ọlọpa.

Yẹyẹnatu:— Hẹn-hẹn nigbana nkọ?

Olotu:— Iyẹn ko to ija ke

Yẹyẹnatu:- Ẹ ti ri ẹmi fẹ gbese Ọlọpa ni yẹn

Olotu:— Rara kẹ, nwọn ni o fẹ pe ẹnikan lẹjọ

Yẹyẹnatu:— Yẹs, ọkunrin oloriburuku kan ni

Olotu:— Kilo de?

Yẹyẹnatu:— Fila lo de

Olotu:— O de ni yẹn

Yẹyẹnatu:— Lati ibo?



Olotu:- Wo o,-jẹ ka sọrọ atata.

Yẹyẹnatu:— Ha! ẹ fẹ sọrọ atata, iyẹn ni ẹo lọ si ọdan l'Eko. Ibẹ ni awọn enia atata ti nsọrọ atata

Olotu:— O dara, kini ẹniti o mu lọ sọdọ Ọlọpa ṣe fun rẹ?

Yẹyẹnatu:— O pe mi ni oniyẹyẹ

Olotu:— Ha! ha! ki iṣe oniyẹyẹ ni ọ ni?

Yẹyẹnatu:— Ẹ jẹ keafulu, bi bẹkọ ma mu ẹnyin na debẹ.

Olotu:- Yẹyẹ, wa jẹbi ẹjọ yi o

Yẹyẹnatu:— Jẹbi ẹjọ wo? igbati o pe mi bẹ tan to tun jẹ ki nwọn fẹ siwe jade

Olotu:— Yẹs, ṣebi iwọ oniyẹyẹ Eko?

Yẹyẹnatu:— Ko sirọ nbẹ soruko to dara ni oniyẹyẹ?

Olotu:- Hẹn! ṣebi orukọ tirẹ sa ni

Yẹyẹnatu:— Iyẹn kọ lofin ti mo fẹ ba ọkunrin yẹn rọ

Olotu:— O dara ofin ewo?

Yẹyẹnatu:— Ha! ẹ ma foju di mi mọ nipa ọrọ ofin o.

Olotu:— Hẹn-hẹn

Yẹyẹnatu:- Eni, nitoripe o npe mi ni oniyẹyẹ, yẹyẹ ni gbogbo aiye npe ọrọ mi. Eji, nitoripe o npe mi ni oniyẹyẹ, gbogbo aiye ni emi iyawo Alapara Ibadan — arifin. Ẹta, nitoripe o npe mi ni oniyẹyẹ, awọn enia ko ni ọwọ fun mi mọ. Ẹrin, nitoripe o npe mi ni oniyẹyẹ, gbogbo ilu a ma ke tẹle mi ti nba nlọ ni titi pe Yẹyẹnatu oni yẹyẹ Eko

Olotu:- Hẹn! ṣugbọn sibẹsibẹ orukọ rẹ sa ni yẹn.

Yẹyẹnatu:- A ni ẹ ko mofin. Ju gbogbo rẹ lọ ṣa Adajọ lo ma da ki i ṣe ẹnyin

Olotu:- A wun mi ṣa lati gbọ ibiti ẹ ba pari rẹ si.

Yẹyẹnatu:- Nwọn ni ẹnikan kowe bere idi ti mo ṣe nlo aṣọ oyinbo.

Olotu:- Yẹs, bẹni

Yẹyẹnatu:- Ṣe ẹ si ti sọ fun un?

Olotu:- Pe bawo?

Yẹyẹnatu:- Pe ọmọ jaiyejaiye ni mi l'Eko

Olotu:- Yẹs! gbogbo wa mọ yẹn kẹ

Yẹyẹnatu:- Gbogbo aṣọ asiko ni mo ni, eyi ti o ba si wun mi ni mo nwọ. Mafọgọta lo l'Eko nisiyi

Olotu:- Hẹn! aṣọ Yoruba nkọ?

YeYẹnatu:- Aṣọ ọwọ ni aṣọ Yoruba kẹ, aṣọ iro ko yatọ, buba ko yatọ, gele ko yatọ lojokojo, ṣugbọn oriṣiriṣi ni ti kaba.

Olotu:- Ṣe o ni kaba faiya silẹ yẹn

Yẹyẹnatu:- O ti, aṣọ asiko ti ọmọluwabi ni mo ni. Nko ni ti awọn kofo.

Olotu:- O ti laju ni yẹn

Yẹyẹnatu:- Olotu!

Olotu:- Hẹn! kini?

Yẹyẹnatu:- Kẹ le mọ pe mo laju mọ si ri yin ni kẹ.

Olotu:- Hẹ! a ni o ko sifilas

Yẹyẹnatu:- O digbose.

# Ọmọ iya ti Islam t'o kari aiye

Iranlọwọ ti o ga julọ eyi ti Islam ṣe fun ilọsiwaju ati ilaju araiye, ni lati da ọmọ iya to daju ti o si kari aiye silẹ.

A gbe ojiṣẹ Mimọ ti Islam dide ni ilẹ Arabia ni igba kan ti iyasọtọ larin ẹya ati awọ, ti gba orilẹ-ede yi kan. Ni iru asiko bayi ni on wa jẹ iṣẹ ti o ti ọrun wa ti ijẹ dọgba-dọgba ti ẹda enia. Awọn Larubawa ko ni ọla ju ẹniti ki iṣe Larubawa lọ, bẹ na si ni awọn ti ki'ṣe Larubawa ko ni ọla ju awọn Larubawa lọ.

Ọmọ Adam ni gbogbo wa jẹ, bẹ si ni iyẹpẹ lafi da Adam, ni Ojiṣẹ Mimọ na kede, Alukurani Mimọ sọ pe: "Ẹniti o bẹru Ọlọrun julọ ninu nyin ni alapọnle julọ ninu nyin ni iwajuẹ Ọlọrun."



*RASHEED-UD-DEEN*

Pẹlu agbara ti ẹmi rẹ ti ko lopin, Ojiṣẹ Mimọ na da si agbari awọn olutẹle rẹ arẹrẹ ti o niyi julọ ti ọmọ iya gbogbo enia. Awọn olutẹle rẹ Muhammad mu iṣe ijẹ dọgba-dọgba yi jẹ titi de ibiti aye pẹkun si.

Ọjọgbọn Gibb kọ ninu iwe rẹ 'Muhammad ati Muhammadanism,' wipe:- "Islam ni arọba ti o niyi, eyiti o jẹ mọ agbọye orilẹede si orilẹ-ede ati isowọpọ. Kosi akojo enia kan ti o ni irufẹ akọsilẹ to dọgba ni ipo ti igbalaye ati ti iṣapa ti o pọ ni oniruru fun araiye. Islam si tun ni agbara lati so awọn orile-ede to yatọ gede-gede ninu ilosi ati arọba wọn papọ.

Igba yowu ti atako awọn akojọ enia ti ọwọ ilẹ Ila-Orun ati ti Iwọ-Orun aiye yio ba yi pada si isowọpọ, Islam ni yio jẹ onilaja larin wọn."

Ọjọgbọn Toynbee tun se itọkasi ninu iwe rẹ "Civilization on Trial" on sọ pe. "Iparun imọ sinu ti orilẹ-ede gẹgẹbi o ti se wa larin awọn Muslim, jẹ ọkan ti o ga ninu awọn aṣeyanri ọmọluwabi ti Islam ati pẹ laiye ẹlẹgbẹ-jẹgbẹ yi, idi wa, gẹgẹbi o ṣi ti nṣẹlẹ, fun itankalẹ iwa rere ti Islam yi.

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

Obunkohun ti o ba de ba enia lojiji tabi lairo tẹlẹ lo ma a nmu ipalara ba enia tabi ti o nfa ibanujẹ wa ba ni.

**ARIES (Mar 20 - Apl 21)** Şişẹ titara-titara lọsẹ yi, maşe fi iṣẹ rẹ şire ma si şe are.

**TAURUS (Apl 22 - May 22)** Fi e t o şe gbogbo işẹ toni, ki o si lo ọgbọn inu rẹ lati fi şe g b o g b o işẹ na.

**GEMINI (May 23 - June 22)** Suru ni ki o ma a fi şe gbogbo işẹ rẹ lọsẹ yi ki ikanju ma ba nkan pupọ jẹ.

**CANCER (June 23 - July 23)** Şe pẹlẹ ki o si f'ara-balẹ wọ ninu ọsẹ yi, ki o ma ba gbe Iọgbọn dani fun rarẹ.

**LEO (July 24 - Aug 24)** Şe suru ki o si şe pẹlẹ nitoripe pupọ ninu awọn nkan ti o ba şe lọsẹ yi, ko ni yori si rere.

**VIRGO (Aug 25 - Sept 23)** Gbogbo awọn nkan o o ti nşẹlẹ si ọ ti ko bọ si rere, ni yio y i p a d a ninu ọsẹ yi, maşe jẹki ẹnu ya ọ.

**LIBRA (Sept 24 - Oct 24)** Iwọ yio jẹ ire işẹ ọwọ rẹ, gbogbo ohun ti o ba de si ọ lọsẹ yi, ire ni yio jẹ.

**SCORPIO (Oct 25 - Nov 23)** Maşe rope aiye sori kodo fun ọ lọsẹ yi, nitoripe ohun g b o g b o ko ni lọ kiakia.

**SAGITTARIUS (Nov 24 - Dec 22)** Ọpọlọpọ ninu awọn ohun ti yio ma şẹlẹ si ọ lọsẹ yi, ire ni gbogbo rẹ yio ma a bọ si.

**CAPRICORN (Dec 23 - Jan 20)** Şe ọpọlọpọ suru lọsẹ yi, nitori lẹhin ọpọ suru ati iforiti, ere pupọ mbẹ fun ọ.

**(AQUARIUS (Jan 20 - Feb 19)** Ojiji ni igba yio yipada fun ọ lọsẹ yi, nitorina pẹlẹ-pẹlẹ di ọwọ rẹ.

**PIESES (Feb 20 - May 19)** Mu ohunkohun ti o ba de si ọ lọsẹ yi girigiri, ayọ ni igbẹhin rẹ yio jẹ

---

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI A NPE NI:-

## "UROXAL"

Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney-Blader fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ẹhin didun eri ile tabi itọ-jijo enia, itọ rirun rukuruku pipọn tabi rirun, lakuregbe Ibaradi wiwo, orunku, ọwọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju aiko le gbe ara konkọn tabi kiakia didaji lorun nigbakugba, ati orişirişi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Meji re ko si ni ilu Naijiria nitorina şora ki awọn eleru tabi awọn oni rọbirọbi ma ta orişi omiran ti ko ni lari fun ọ ma şe gba a rara o! Owo rẹ jẹ şile mẹfa abọ (6/6d) owo ọkọ şile meji abọ (2/6d) bere egbogi yi ni şọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-



ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET, YABA. PHONE: 22878

**Waterloo Medicine Stores**
**Palm church Street, Lagos. P. O. Box 333, Lagos**
**Phone: 22878 Nigerian,** (Oja ita Faji)

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

WATERLOO MEDICINE STORES
11A' FAGBEWESA STREET, OSHOGBO

---

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI:—

## RiCHALET FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi Iṣẹ rẹ lara enia o si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o buburu ti o ba wa ni nu "ẸJẸ ARA" bi Mọnọmọnọ.

Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta kakiri ni owo pọọku, adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn şe e w ọ awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npota ni Ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Oyibara wa ti mọ ifẹ awọn egbogi bawọnyẹn a ma ba ojulowo egbogi atata ti aranşẹ fun tita lati awọn ilu amani, Faranse, ati ti a w ọ n Tatambulu si Italijẹ mọ daju pe bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le şe ọ. Lakuregbe, orişirişi Inarun, Ojuşuşu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ-Iba, arun-Ẹdọki, Aya didun Tanpara ati Ekuru laya

Ara riro, Lapalapa, Egbo-Ẹsẹ Amodi Apo Ile itọ, ẹhin didun tabi Ibaradi riro pẹlu. Egbogi Risalẹt a ma pa gbogbo kokoro buruku to wa n i n u ẹjẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pelu. Şa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ dajudaju Iwọ yio ma rohin rẹ fun ẹlominran p ẹ l u nigbakugba.

**Waterloo Medicine Stores,**
**8, Palmchurch Street, Lagos,**
**Phone: 22878 Nigerian, (Ọja ita Faji)**

NIGERIAN MEDICINE STORES
TINUBU STREET, LAGOS PHONE:- 20278.

ADEDUN CHEMISTS,
4, WAKEMAN STREET, PHONE 22878 YABA.

---

Advert. 134

## NOTICE

*NIGERIAN HONOURS, DECORAITIONS AND AWARDS*

The National Committee on the award of Nigeria n Honour would welcome suggestions from the general public on the following questions:-

(i) Do you consider that there should be only one set of National Awards, or do you consider that there should also be Regional Awards either for services rendered to the Regions or in recognition of visiting foreing dignitaries?

(ii) Do you consider that such awards should take the form of:-
(a) titles, which qualify recipients to use letters after their names, or
(b) decorations, which qualify recipients to wear medals on ceremonial occasions, or
(c) both, or
(d) neither?

(iii) Do you consider that Foreign Honours should be accepted by Nigerians, with or without the approval of the Federal Government?

2. Please address all communications to:-
*The Secretary,*
National Committee on Nigerian Honours,
c/o Cabinet Office,
LAGOS.

3. It will be appreciated if your suggestions are forward to the Secretary not later than 30th of September, 1962.

# EYI NI AWỌN ỌJỌ ỌJA ILẸ YORUBA

## ỌJỌ AJE SEPTEMBER 17 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, Ejinrin |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN | Akeroro, Idofin, Lagun, Ṣagbe, Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode - Remo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi - Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilarọ, Ọja - Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ ETI SEPTEMBER 21 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN | Akeroro, Idofin, Lagun, Ṣagbe, Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaosu, Ogere, Irolu, Itele, Ode - Remo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi - Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilarọ, Ọja—Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ IṢẸGUN SEPTEMBER 18 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun - Eko, Ojuwoye |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ilẹ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ẹgbeda, Babalokuta |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope Iṣara, Imodi, Ishan |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọ Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo—Aiyedun |

## ỌJỌ ABAMẸTA SEPTEMBER 22 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Ikosi, Ẹpẹ |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ogburo, Ẹgbeda, Babalokuta |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpẹ, Ishan, Isara, Imodi |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọ, Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo – Aiyedun |

## ỌJỌ'RU SEPTEMBER 19 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodeke, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowo, Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Okun - Ọwa, Erunwọn, Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ AIKU SEPTEMBER 23 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ILU |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, Badagry |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodeke, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowọ, Temidire |
| IJẸBU | Ikenne, Okun-Ọwa, Erunwa Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ SEPTEMBER 20 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Agege, Ikeja |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla, Ajegunlẹ, Idọgọ |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ, Owode, Igbo-ọra |
| IJẸBU | Ibefun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹsha, Ijẹbu, Iṣara Imodi |
| IJẸSHA | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun Ijẹbu,-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiẹmi |
| EIKTI | Okemesi, Ifaki. |

## ỌJỌ AJE SEPTEMBER 24 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikeja, Agege, Ebute-Ero, Ọjọ Ajido |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla, Ajegunlẹ, Idọgọ |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ, Owode, Igbo-ọra |
| IJẸBU | Ibefun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹsha-Ijẹbu, Isara, Imodi |
| IJẸSHA | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi, Ifaki |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

*Lati Ọwọ EJON'GBORO*

*LỌNDỌNU*

Ipade awọn Alakoso Ijọba awọn Ilu ti o ti gba Ominira bẹrẹ ni Ilu Oyinbo ninu Ọsẹ ti o kọja yi.

*EZZA:—*

Ọkunrin kan Nyiyina Okobo gburo ariwo kan nibiti o ko iṣu Oko rẹ pamosi, bi o si ti jade lati wo awọn ti npariwo, loba ri awọn Ọkunrin mẹta nigbati yio ti bere ọrọ lọwọ wọn nwọn ti ge e ni Ọwọ mejeji ati ẹsẹ kan o si wa ni ile-iwosan nisisiyi, Awọn Ọlọpa nwa awọn ti o siṣẹ ibi yi.

*IBADAN:—*

Ẹgbaarin (8,000) Ọmọ ni nwọn bi si ile-iwosan AdeỌyọ larin Ọdun kan, ẹdẹgbajọ (1,500) awọn alaisan ni nwọn si ntọju ni ọjọ kan ṣoṣo

*ALJIRIA:—*

Akọwe agba, Ogbeni Mohammed Khider, ti sọ ninu ọrọ-asọrọmagbesi wipe Ija igboro ti o wa ninu ilu na ti pari ṣugbọn ki gbogbo awọn ọmọ Ogun duro si ibiti nwọn wa.

*GEORGIA:-*

Ṣọọṣi meji lo jona raurau ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi nigbati ọkunrin kan ṣa ina si i. Awọn ọlọpa si ti mu ọkunrin na.

*EKO:-*

Enia mẹta ni awọn Ọlọpa gbe oku wọn larin ọsẹ ti o kọja yi Nwọn ko si mọ awọn enia wọn tabi orukọ wọn.

*GHANA:—*

Obinrin Oyinbo kan ati awọn ọmọ rẹ meji ni mọto wọn takiti sinu Odo gbogbo wọn si ku ati ọmọ wọn.

*ABAGANA:-*

Awọn Ọlọpa ti pe igba (200) enia lati bere ọrọ lọwọ wọn nitoripe awọn kan tina bọle nitori ede-aiyede kan ti o wa lori ilẹ wọn.

Awọn enia diẹ ni ina ṣe ijamba fun, ẹru ti o jona si to ẹgba ponun (£2, 000).

*MANILA:—*

Obinrin aboyun kan ati ọdọmọde kan ni ọkọ kenu wọn dojide lagbami, nwon ko si ri oku wọn

*LUZON:-*

Agbara ojo gbe enia mesan lọ ninu alagbalugbu ojo kan ti o rọ ninu ọsẹ ti o kọja yi.

BAGUIO

Baba kan, Iyawo rẹ ati awọn ọmọ wọn mẹta ni ilẹ gbe, mi nigba ti ilẹ deede yanu lojiji. Gbogbo wọn si di ẹni Orun.

NKALAGU

Okunrin kan, Dominic jade ninu ile lọ si ibi iṣọ rẹ Ṣugbọn ko pada de ba iyawo rẹ mọ Awọn enia si ti mu Iyawo na.

*KENYA:-*

Ogbẹni Tom Mboya, minista iṣẹ ti kesi Ijọba Gẹẹsi lati ṣe iranlọwọ fun ẹdẹgbajọ (15,000) awọn oloko ti o wa ni ilu Kenya ki eni kọọkan wọn le ma a gba ogun ponun (£20) lo soosu.

*VATICAN—*

Ẹniọwọ Pope John, ti iṣe Olori Ijọ awọn Aguda ti kesi gobgbo agbaiye ninu ẹrọ asọrọmagbesi ninu ọsẹ yi wipe ki irẹpọ wa ni gbogbo aiye larin Oriṣi ede kan ati si ekeji.

*ONITSHA:-*

Awọn Ọlọpa ti mu enia merindinlogun fun ẹsun pe nwọn ri ewe taba "IGBO" ti iye owo rẹ jẹ ọkẹ kan o le ẹgbedogbon ponun (£25,000) ninu oko kan si agbegbe Ogbokwo.

## Apọda kan fi adọta pọnun (£50) Tanran

KADUNA:- Ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni Adajọ Kotu kan ṣe idajọ pe ki Ọdaran kan Dick Idomah ẹni ọgbọn ọdun fi adọta pọnun (£50) tanran si Kọtu tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu mẹfa nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn Olọpa fi sun .

Ọlọpa ti o ba Ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye fun Kotu pe Ọdaran na ṣaiṣẹ ọda ile kikun Isbẹ awọn Oyinbo ti nwọn npe ni (G. Cappa) O si ji wọn ni idaji gorodomu ọda ti iye owo rẹ jẹ pọnun mejila abọ (£12:10/-)

Ọdaran na sọ wipe on ko jẹbi nitoripe iṣẹ wọn ni on fẹ lo ọda na fun ki on to gbe e jade.

## ỌWỌ TẸ ISANSA ẸLẸWỌN KAN

IJU:— Idaamu nla ba ọga awọn ẹlẹwọn nigbati ẹlẹwọn kan Oji Nwanwa sa mọ wọn lọwọ ni ọjọ iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa si ti bẹrẹ wa a, ki nwọn to ri i ni Aro Chuchukwu ni ọjọ kẹta.

Awọn Ọlọpa sọ fun Oniwe IROHIN IMỌLẸ wa pe oniṣegun ni ẹlẹwọn na, ṣugbọn nigbati o fẹ pa iyawo rẹ ati ẹgbọn rẹ ni o ba fi de Ọgba ẹwọn.

## MAJẸKODUNMI LUGBADI OFIN

IBADAN:— Awọn Ọlọpa mu Ọdaran kan Afọlabi Majẹkodunmi wa si siwaju Adajọ Ile ẹjọ kekere kan fun ẹsun pe, o gba awamọto ti ko ni Iwe aṣẹ lọwọ.

Ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye niwaju Adajọ wipe, Odaran na jẹ Oloye kan, ti o si nta ẹpo mọto Nigbati awọn ri i ninu mọto ti awọn si ṣe iwadi lọwọ rẹ pe iwe ti o fi nwa mọto da ? ti ko si ni iwe na lọwọ ni awọn Ọlọpa ba fi mu u wa Tẹsan.

Ọdaran na gba pe on jẹbi ni Adajọ ba ni ki o lọ fi pọnun mẹdogun (£15) tanran si kotu tabi ki o lọ si ẹwọn Oṣu meji.

## IDIJE! IDIJE!!

A fi eyi kede fun gbogbo awọn Onkawe IROHIN IMỌLẸ ati awọn Ọmọ karọ-o-jire pe, a nlẹ

### ITAN LEDE YORUBA

Eyiti ẹnikẹni ko ti tẹ jade ninu iwe ri tabi ti nwọn ko ti sọ lori Radio ri; ẹnikẹni ti o ba si bori yio gba.—

**(£1 : 1/-)** PỌNUN KAN ṢILE KAN

*AKIYESI*:- Kọ itan rẹ ki o han rekete, ti ẹniti ko ba han ao fa a ya ni, ki o si mọ dajudaju pe ko si ipin ninu Idije na ITAN eniti o ba si dara ju ni ao tẹ jade ninu IWE IROHIN IMỌLẸ yi, ao si fi Pọnun kan ṣile kan (£1 : 1/-) (Postal Order) ranṣẹ si i. A ko kọ ọmọde tabi agbalagba.

Fi Stamp Tọrọ **(3D)** ranṣẹ fun gbigbe Pọnun kan Ṣile kan (£1 : 1/-) ti o ba je pada si ọ, ki o ge ibiti Idije yi wa, kio si fi ranṣẹ pẹlu Stamp Tọrọ rẹ si wa. Ẹnikẹni ti ko ba ge Idije tirẹ ranṣẹ si wa, ti o ba jẹ owo na, a ko ni fi ranṣẹ si i, a ko si ni fun un ni Stamp Tọrọ rẹ.

*ORUKỌ*______________________

*IBUGBE*______________________

______________________

Fi itan rẹ ranṣẹ si:-

**OLOTU IROHIN IMỌLẸ**
16, Bamgbose Street, Lagos.

## "ENIA DUDU NDIDE"

Awọn Oniṣowo U. A. C. ti ni Sinima wọn ti nwọn npe ni "ENIA DUDU NDIDE" han gbogbo enia l'Eko ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi

Awọn alaṣẹ U. A. C. si ti ṣe ipinnu lati fi Sinima na han fun gbogbo awọn Ọmọ Naijiria ti nwọn wa ni Ibadan, Enugu, Kaduna, ki awọn enia na le mọ ohun ribiribi ti awọn enia dudu nṣe

## ỌRẸ MEJI WẸWỌN ỌDUN MEJI

Awọn Ọlọpa mu awọn Ọdaran meji kan, Onwuka Kalu ẹni Ọdun mẹdọgbọn ati Onuoka Kalo wa siwaju Adajọ ile ẹjọ giga kan fun ẹsun jibiti.

Alaye ti awọn Ọlọpa ṣe fun kotu na ni wipe, nwọn fi ipa gba pọnun meje lọwọ Ọgbẹni Callistus Enyieku ti o ngbe 24, ojoto Street, ni ọjọ kejilelogun oṣu kejo ọdun yi.

Nigbati awọn Ọdaran na ro jọ ti nwọn si gba wipe awọn jẹbi ni Adajọ ba ni ki nwọn o lọ fi ẹwọn Ọdun mejimeji jura.

## Nigerian Ports Authority

INVITATION TO TENDER

CONTRACT FOR SUPPLY OF LABOUR FOR
(a) "C" WAREHOUSE, APAPA QUAY
(b) "D" WAREHOUSE, APAPA QUAY.

The Nigerian Ports Authority invite tenders from Contractors to supply experienced labour with adequate supervision for the handling of cargo at "C" and "D" Warehouses, Apapa Quay. The former Warehouse is still under construction but should be completed before the end of this year.

2. Tenders which must be submitted on forms provided by the Authority for each Warehouse separately and returned in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR LABOUR "C" (or "D" as the case may be) WAREHOUSE" should be addressed to the Secretary to the Authority, Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, so as to reach him not later than 4 o'clock in the afternoon of **Monday, 8th October, 1962. Not Monday, 17th September, 1962,** as shown in N. P. A. Notice No. 761.

3. Tenderers may tender for either one or both of the two Warehouses.

4. Persons tendering for "C" Warehouse must use the Form of Tender bearing "C" Warehouse and persons tendering for "D" Wharehouse must use the Form of Tender bearing "D" Warehouse.

5. The issue of an official form of tender will be subject to a deposit of £10 for each warehouse, payable to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quay. The deposit will be returned on receipt of a bona fide tender.

6. Only applications from labour contractors who have had experience in similar work will be considered, and the Authority do not bind themselves to accept the lowest or any tender.

7. Applicants wishing to view either "C" or "D" Warehouse or both before submitting tenders, should apply in person to Chief Traffic and Commercial Manager, Apapa Quay.

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority*

N. P. A. Notice No. 764.
10th September, 1962.

**Itan Iṣẹdalẹ Yoruba ti bẹrẹ si jade ninu iwe Irohin Imọlẹ. Wo oju ewe kẹrin, maa ka Irohin Imọlẹ deede.**

*Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495, Phone 21985, Lagos Olotu: E. A. Adeniji 24, Ollyide Street, Odo—Abọrẹ Mushin.*